Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.


# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO


Akiyesi Pataki

A fi nę yi şe ikede si awọn Aşoju Iwe IrohinEleti Ofe kakiri agbaiye wipe, enikẹni ti ko ba fi owo ti o ti je ranşę si wa, o pe lejo, ako si ni fi Iwe Irohin ranşę si onibę mọ.


VOL. XI No. 621. LAGOS, SATURDAY, APRIL 25 — MAY 1, 1959. KOBO MEJI (2d)


# Awon Enia Metadinlogun Moribo Ninu Ajaga Ejo Apania.

Ọkunrin kan ti o njẹ Shittu Ajao ni eniti adajo kotu giga tilu Ibadan ti da lẹbi iku ni ọdun to kọja, nitori ti o pa ọkọ ọmọ rẹ kan ti o njẹ Adeshina. Ọkunrin yi kanna ni adajo kotu kotẹmilọrun tun da lẹbi wipe ki nwon lo yẹgi fun.Ẹniti yio ku pẹlu rẹ ni Gbadamosi Ilọri ti o jẹ ọrẹ rẹ.

Lasiko ti nwon nse ẹjọ awon apania nwonyi, ọlopa kan sọ wi e nigbati awon mu shittu Ajao, o so fun awon wipe, emi niyi, nko jẹ salo ,emi jẹ okan ninu awon to pa oko omo mi ati pe bi ko ba si ti oro egbe kose egbe ni, ko si ohun ti mo le fi pa ano mi na.

Ẹyin ọkawe wa yio ranti wipe awọn enia ti idajọ da lẹbi iyẹgi-mọ-lẹsẹ pa nigbati nwọn se ẹjọ awọn ti nwọn fi sun esun apania lọdun tokọja po jojo şugbọn pupọ ninu awọn enia na ni Kotu Kotẹmilọrun ti o jẹ ti awọn adajọ agba ti da silẹ pe nwọn ko jẹbi iku.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Througout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE

1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Nathaniger London.
Head Office Representatives in London
E.Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.


## Sir John Macpherson Yio Gba Isinmi

Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Sir John Macpherson ti o kọkọ jẹ oye Gomina Agba (Governor General) nile yi, ki o to tun pada lo silu oyinbo lati tun lọ bẹrẹ işẹ ni ile işẹ ijọba Gẹsi.



Nisisiyi, ogo wa doju ikẹ e o ti lati mowọ kuro ninu işẹ ijọba ki o si gba isinmi ifẹhinti. Ẹniti a gbọ wipe yio rọpo rẹ ninu işẹ ijọba ni Sir Hilton Poynton.

## Lagos Race Club

RECLASSIFICATION OF HORSES

FROM TOP TO MIDDLE DIVISION — Baddal
— Big Demon
Blue Demon

FROM BOTTOM TO MIDDLE DIVISION:-
Dania
Royal Ruby

FROM MIDDLE TO BOTTOM DIVISON.-
Federal Court, Gamble for Love
Hot Devil — Lucky Day
Malaria — My Joy
No Race — Sea Storm.
Tabu — Taiba
The Solicitor — Toreul
White Demon.
White Sugar (late Panama) —
Yes Alfah Inana (late Palmarine)

FROM MIDDLE TO TOP DIVISION:- Cyclops Danburk, Ginger, Love Boy, Sultan, Taytell.

## Ipade Ajo Babalawo

ỌDUN IPỌLA, 15th EBIBI (MAY) 1959.

Ajọdun ọdun Ipela ti odun ni an şe ni Agbara Ẹlẹda, ni ọjọ eti ọjọ kẹ ogun oşu Ebibi (May), 1959, ni "Ile Ijuba Odumare", ni ayika Orişa ẹda ti Odumare pẹlu ilu ati ifọn.

Ninu ajọyọ ajọdun wa ọdunni, elan ile Ijuba wa, ki a bẹbẹ gidigidi fun "Ijọba rere, olotitọ ati alafia" na ninu awọn ijọba mẹrẹrin ti no di "Ibo" fun nisn ọdunni, ni ki a b'ori ninu ibo gbogbogbo igba ominira fun apapọ erikẹ-ede yi. Ọrunmila a gb'ẹbun yin Aşẹ Ọdun ọdunni nyabo Aşẹ.

Olulana Ijọ ti (A) Ọrunmila Agbaiye'

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL XI. NO. 621. SATURDAY APRIL 25 - MAY 1, 1959


## Asofo Ko Gba Egba a...

Ibi ọpẹ l'omọ, ni ọrọ owe awọn Yoruba ti a fi ṣe ẹsin asayan ọrọ wosika wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọrẹ ati ọkawe wa lori iwa awọn oni sọndi-sọndi ti ko mọ wipe iwa ṣinnasi, tabi iṣe keta ọmọ-ẹnikeji ẹni jẹ eyiti Ọlọrun ko fẹ ti ko si yọnu si rara, nitoripe ọrọ Ọlọrun ti fi han wa ninu Iwe Mimọ pe 'Iwọ abanijẹ nigbati iwọ ba dẹkun iwa ibanijẹ, nigbana ni ao ba ọ jẹ'

Iwa ibajẹ ti a nsọ yi jẹ iwa ti o wọpọ nibi iṣẹ ti awọn enia palanta yio ma fi wa oju rere ọga tabi ti awọn agbanisiṣẹ, daju-daju, bi o ti wu ki o le pẹ to, iṣẹ yio j'abọ fun oniṣẹ, ohun pataki ti a nilati mọ ni wipe ko si ohun kan ti enia le ṣe lode aiye yi ti oluwarẹ ko ni jere rẹ, yala ni rere tabi ni buburu.

Ọrọ mimọ Ọlọrun fihan wa wipe 'gbogbo ọrọ buburu ti enia nsọ, nwọn o jihin rẹ ni ọjọ idajọ". Ọrọ sisọ lasan ni eyi, ki a ṣẹṣẹ wa sọ ti iwa jamba si ọmọnikeji ẹni. Ẹ ṣọra yin.






## Duke Of Gloucester Yio Be Nig. Wo

A gbọ irohin pe ijoye ilu Oyinbo kan ti o jẹ idile ọba Gẹsi, ti a npe ni Duke of Gloucester mbọ wa sile Nigeria ninu oṣu May, 1959, lati wa karakun anaki aṣe iṣakoso ara ẹni fun agbegbe ilẹ Hausa.

A gbọ pe awọn Hausa ti nṣe ipalẹmọ ohun ti nwọn yio fi ṣe alejo na. Inu Ijoye na a si ma dun si ẹni-kẹni ti o ba le fun wọn ni irohin nipa ilẹ Afrika ati paapa nipa ilẹ Nigeria.

# Itan Oloye Awolowo Niba Soki.



Oloye Awolowo jẹ omo agbẹ nigba ewe rẹ, Nigbati baba rẹ ṣalaisi lo fi ilewe silẹ lati ma lọ gbe odo awon ẹbi kakiri. O nlo si oko lati lo ṣe igi, o si ngbe wa si oja wa ta, iba owo ti o ba ri kojo lo fi nsanwo ilewe, Nigbati o di omo odun merindilogun lo bẹrẹ ilewe giga ti Methodist, o jẹ ẹni kan ti o fẹran ẹsin Ọlọrun pupọ, ko si nja ninu sosi lojo kan.

O di ọkan ninu awon oluko College, o ko Shorthand Typist funra re ki o to wa di oniwe irohin. O gba oye B. Com; o si tun gboye lọya.




# Olopa Fi Esun Kun Esun Egbe Omo Aiye

ILORIN. Awon egbe kan ti nwon npe ni egbe omo aiye ti awon olopa, ramu ni oko Ilorin, ti nwon ko orișa won șigidi, ado șere ati esu won, awon eniti nwon fi sun esun ese mejila, ti awon omo egbe na si so pe awon ko jebi eyikeyi ninu esun na, ni nwon gbe dewaju adajo șugbon adajo na da won silę lori esun mejila.

A tun gbo pe, awon enia na koiti jade kuro ninu kotu nigbati olopa tun ra won mu fun esun titun miran o si je esun metalelogun, enia mejo ni nwon da sile pe kio ma lo ni alafia nwon ko lejo lati ba won ro. Oruko won ni nwonyi

Sinabu Abeo, Momodu Alao, Sanusi Awelewa, Adebinpe, Bale, Yakubu Alao, Aileru Alao, Akanni Oke, ati Adeyemi Alabi. Olori awon egbe omo aiye so fun adajo pe awon orisa on, ko nse wipe o kan wa nibe lasan awon Șigidi on, a ma je iyan.

Adajo da Awero ti o nse olori awon egbe na ati awon enia meje yoku lebi o si fi won si ewon ti apapo re je odun merinla ati osu mefa.


NISISIYI!

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA...

AWON ONIȘOWO

THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.

YIO MA ȘE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

Ale fi Gas pelu Meter re sinu ile ti a ngbe Koni agbekiri. Ko si ni șalai muna wa nigba kan. Ko lewu, o rorun, lilo re din inawo ku.

ENYIN KOLEKOLE, ONILE ATI ENIKENI TI O BA FE LILO RE KI

O KOWE FUN ALAYE KIKUN LODO :-

NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.

2, ITAPEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELEPHONE 55295.

Iye owo re ati gbogbo alaye nipa re ni ao se fun yin lofe.


## Ija Osanyin Ati Onitumpulu

(APA III)

Bi Orișa Osanyin ti npada lo sile, ese re dabi eyiti o jin sinu ere, nibiti ere ko si. Osanyin gbe ese re ni agbeti. O p'ofo-pofo ese re ko le yo ko si s'enikan ti o le pe nitosi re.

Tohun-tenu beni Orișa Dada npada bo wa sile lati wa ba won șe aisun ti oku iya Oduduwa, nigbati o ri iru irora ti o wa fun Osanyin anu șe e o yo ada re lati fi gbaa sile, beni Onitumpulu tun de, o ni ki Dada kuro nibe: Dada ko dahun ni Onitumpulu ba fi owo ja ijakun ninu igbo o si ko egba bo Dada kikan-kikan.

Nigbati Adirun ti o nșe omo chio Dada ri iru iya ti a fi nje oluware bayi o sare lo pe Orișa Șango ni awujo awon agba ni ale ode Ife. Nigbati o gbo pe, enikan nfiya je egbon re kian, lo dide, ko tile dagbere fun enikan.

O dide pelu igbona ara oju re pon, gbogbo ara re ngbon, eefi nyo ni oju inu, eti ati enu re. Adirun si mu Șango lo sibiti awon gbe nfiya je Dada, inu re baje lati ma gbo igbe egbon re, o pe ofo ojo si șu, nibiti Onitumpulu gbe nna Dada lowo ni ara gbe san pa a.

Lati ojo na ni Onitumpulu ti jade kuro ni aiye. E ma ka iwe irohin Eleti-Ofe, eo ma gbo nipa ohun ti o șele nibi aisun oku iya Oduduwa.

(Koiti pari)

## THEOPHILUS SHOGA LO GBEWA

EKO Odomokunrin kan ti a npe ni Theophilus Șoga, ti o nșe ișe nibi ina Lentiriki on pelu okunrin kan ti nwon npe ni Yaya Ogunwumi ti on na șișe ina kanna yi, ni adajo fi si ewon oșu merin ati pe ki nwon san Poun medogun si Kotu

Ese ti a gbo wipe Șoga șe ni pe, o fi ona eru ati jibiti gba adota Poun lowo enikan to ngbe Mushin, enikeji re Yaya Ogunwumi ni a gbo pe, o lo bura eke.

Awon odaran na so pe adajo ti o koko dajo won so pe on gba pe oogun mbe.

## Irin Ajo Lo Si Meka Ati Medina

(Lati Owo Alhaji)

Nitori gbogbo owo ni oluwarę ti san ni Jidda (£8 - 10s 6d gbogbo siga to ' a ni Eko (Lagos) ni awon ta ni Jidda.

Jidda si męcca ję (42 miles) ibuso mejilelogoji. ki ę to fi Jidda silę ao şe aluwala ao si wę iwę Harami, Lęhin ti a ba ti wę iwę na tan a ko gbodo fi aso kankan kan ara mo ayafi ka gbe Harami wo. Lęhin ti a ba gbe Harami wo tan ao yan Nafila meji, ao wa ke Labeka Alahumma Labeka ati bębę lęhin eyi ao di ęru wa, ao ko si moto, odi mecca niyen. Bi a ba de mecca a ko gbodo wole ao ko ęru wa si ode ao şe aluwala odi ile Oluwa niyen. Bi a ba de ibę, ao gba buba Salami wole, lęhina ao yi Ikaba po ni 7 times bi a ba yi ile Oluwa po tan ao pon Ajara-Lasiwado la.

Lęhina ao fi omi-semi semi wę, lęhina ao sa Safa oriha, 7 times ao wa fori Bi a ba de macca no Haya ile ni o ile odo Alhaji Buraimo enikankan yio san £18 tabi £20 ile tirę ko jinna si Kabba ile yi wa fun awon to ba ni owo lowo dada. Kosi ibusun nibę kosi onję nibę. Ire fun rara rę lo ma wa ibusun ti o ma fi o ma fi sun ati onję ti o ma je şugbon ti oluwarę koba ni owo lowo dada. oluwarę yio de si Mosfala ile ibę koju £6. lo Mosfala yi to 10 minutes "Idamęta ibuso kan agogo meji pelu abo ęru tiwa ni nwon ki asuba ni Macca (2. 30 a.m.) Nitori ilę ti mo nigbana.

Gęgębi moti wi ni oke iwe yi wipe bi ę ba sa safa- moriba tan ao tun fari lęhin eyi ti ę ba dele, ao bo Harami wa silę oluwa rę le lo aşo to ba fę, ki o ma lo Tawafi ni gbogbo igba ao wo moto lati Mecca wa si Jidda iyen je buso mętalelogoji (43 miles) lehinna ao tun woko ofurufu lati Jidda wa si Madina ao lo wakati kan pęlu abo (1 1 2 hrs) ninu oko ofurufu, lęhin ti a ba bo silę ninu oko ofurufu awon oloko ofurufu yio fi bosi "Bus" won gbe yin wa si ilu Madina. Iyen to buso meji (2 miles).

(Koiti pari)

## Itan Elegbeje Ado.

(Lati Owo Y. Adę. Boraimoh)

### IJA PARI

Oba bere oro nisisiyi. Kini o ko lo sepe aiye re dun ju ti emi lo? Baba yi da Oba lohun pe, Otito ni Ododo sini pelu aiye mi dun ju ti tiyin lo ati onokona ki isi se agbara mi bi kose agbara Edumare ti o da iwo papa Oba tun ni ki o tun ro Baba yi tun so bakanna.

Oba pase pe ki won fi ida (Sword) ge ni ori, beni won tun ni de fiti ile pe iyawo re bi omo meta (Ibeta) imu Oba baje gidigidi, lehinna ni o ni ki won fi sile, ni o ba bo gbogbo eso ara re fun Baba agbe yi, agbe na wa di Olola ati Ogla.

Baba agbe yi bere oro bayi pe, mo dupe lowo re Oluwa, Olodumare to da aiye ati orun fun ore ola-ola ti o se fun mi loni ati agbati o ti da mi si orile aiye yi.

Loyin ara mi Okunrin ni, Obirin, lagba lomode, ati alejo pelu aiye ta ledara ju tani dun jo nino ti emi pelu Oba? gbogbo won ni ti e lo dun ju ti Oba lo. Baba yi wa ba ririrere lo si ile re ni ojo na.

Itan yi ko wa pe ki a ma beru Olorun Oba Oga Ogo ju enia lo, ti Olorun ni yio se ti o ba ti gbekele, ti o ko se iyemeji, yio lati pelu re.

Ko ye pe ki a mase keta ara wa rara ti Olorun ni yio se o.

## Loya Ati Olowo-ele Gbija Niwaju Adajo.

YABA. Okunrin olowo-ele kan pe Okunrin kan lejo owo ti o je sinu kotu. Eniti o je gbese na gba loya kan ti o ba a se ejo na, tobe ti adajo fi ni ki o lo san'wo na, ni poun kokan lo sosu lati ipari osu April 1959 Apapo gbogbo owo na je pounmokandinlogota.

Agbo wipe eyi ko dun mo Okunrin olowoele na ninu. Olowoele na jade kuro ninu apoti eri, o wa fe lati gba ibiti loya Sanyajoko o si koja. so bayi si loya na wipe, jowo j e k i o l u n k o ja lo o jare.

Loya-dahun pe, ko si aye fun o ni hin lati gba koja lo gba ibomiran.

Olowo-ele Iro lo pa, ihin gan ni emi yio gba koja, o fe o ko

Loya na wi fun pe, jade kuro nihin o jare!

Nigbati ohun awon mejeji se nle ju ninu kotu ni adajo ba pe enikini ati enikeji sinu yara, o si pari ija na fun torun-tosi won.

## IFE FADAKA NIYI



Okan ninu awon okawe wa lo kowe si wa wipe, nigba gbogbo ni on ma nka ninu awon iwe irohin wa wipe awon kan sere, asi fun awon ti o bori ninu ere na ni ife Fadaka.

Inu wa yio dun bi Olotu iwe Irohin Eleti-Ofe bale se aworan ife Fadaka kan sinu iwe irohin re, ki a ba le mo gegebi ife na tiri loju.

Aworan wa ti a nwo yi je okan ninu awon ife Fadaka ti nwon ngba nilu Eko larin awon oşere idaraya.

## Ohun To Sele Ni Bi Oku Iya Oduduwa

(APa III)

Lati iku iya Oduduwa yi, o di awon Irunmole meji tio p a r e kuro larin awon Orisa. Ekini ni Gbohun-gbohun ekeji ni Onitompulo.

Lojo ti nwon f e se Erinla oku iya Odua ni edekoyede be sile larin meji Ajagbo-dudu ati Elekuru. Elekuru je alwo Ajantala, Ajagbodudu je omo Oba ni apa ile Benin.

Nigbati awon jeun osun tan ni nwon bere si fi ija Osanyin ati Onitumpelu ta chin gbogbo bi awon ti nsoro daruko Osanyin ni inu bere si bi Elekuru, tobe ti o fi da si oro n a wipe e wo mi na, bi ę k o b a y e daruko Osanyin, ogo tu gbogbo uyin k a, Ajagbodudu d i d e, o s i pakuru m o Elekuru, o wipe, kai iwo yi ma go, agbara wo ni iwo yio fi t u wa k a? Gbon riye-riye ki a wo o.

Elekuru seju si a w o n ti o je ore tire, lehin ti nwon lo tan ni Ele kuru gbon riye-riye kokoro Oyin si da bo won, olukuluku ko'mọju ti o fi salo.

Koiti Pari

## Onje Ale A jer'o-run

EKO. Omobinrin kan ti ko ju omo ogbon odun lo ni ojo ori re ni agbo wipe o ro oka amala bi osi ti nje onje na lowo beni o yi subu lojiji, ibe n i Olojo gbe de si.

A gbo wipe Obinrin na bi omo meji sile, lai ko se aisan ki o to ku, awon ti ebi o ku re lo fun ayewo nile Dokita l'oke Ebute-Metta.

## ỌMỌ KEKERE !'UWA IPATA NILE ISE

EKO. A gbọ irohin wipe ọmọde kekere kan lo sodo awon Majamaja lati lo bere aja re ti nwon mu, nitori on ko ri aja na ki o pada wale tabi lati iwon ọjọ meta.

Awon osise maja-maja dide lọ wo awon aja ti nwon mu sugbon ko si aja ti omo na nibe. Ọmode na ko gbagbo, o si bẹrẹ si pariwo ninu ile isẹ tobẹ, ti nwon ni lati le sode.

Nigbati omo na de ode, o bẹrẹ si soko lati ode sinu ile isẹ ibe ni ọlopa ti ramu. Adajo so wipe, anu se on jọjo lati ri pe edaran na je omo ilewe. Nitorina on fi eyi fa a leti, ko gbodo tun wa siwaju on mo fun esun kesun.

Nitorina ki o lọ san ṣile marun tabi ẹwon ojo mẹta.

## ARUN LỌRUN-LỌRUN GBOJIKAN NILẸ HAUSA

OKE-ỌYA. Irohin ti a ngbọ kakiri nihin ati lọhun ni ti arun lọrun-lorun (Menigitis) ti o gbojikan kakiri ilẹ Hausa, ti o npa aja ti o npa adiẹ, ti o nṣe jamba oniko iku wa ba awon enia pelu.

Lenu ọsẹ ti o koja lọ yi, a gbọ wipe, o ti le ni iwon adoje enia ti arun yi ti pa danu. Ijọba se ikede wipe, ki awon enia mase fi ọrọ arun lọrun-lọrun yi ṣere rara, ki nwon masi ṣe kẹrẹgbẹ pẹlu rẹ. Nigerẹ ti nwon ba ti ṣakiyesi arun yi lara won, ile Dokita tabi Hospital ni ki nwon ma lo, nitoriṣe awon Dokita lo me egbogi ti nwon ma lo fun oluware. Ẹnyin ero lọna, o yẹ ki ẹ ma lo ri Dokita nyin ki e to koja lo si Oke-Ọya.

## IYAWO BẸRẸ ERE PIRIPITI

YABA Ọkunrin kan ti nwọn ṣeṣẹ fi iyawo ranṣẹ si lati ilu wọn, iyawo lo ro aṣọ dẹdẹ, o gba dẹdẹ, o joko ni arin ọgba, awọn enia rẹ si pagbo yika, nwọn nsure fun. Awọn enia si duro yika. Nibiti nwọn nṣe edura yi lọwọ ni alangba kekere kan sare ko si abẹ aṣọ iyawo.

Emmọ! kini a ri yi, ni iyawo ba dide, ti o si bẹrẹ si gba ara re ni abara ti o si dabi eyiti o njo ilu gẹdẹdẹ.

Agbako ! ori ẹde, nigbati awon ẹnia ri bayi ni gbogbo enia ba salọ. Iyawo papa koiti mọ kini ohun ti o fa sababi n ? Nigbana ni alangba ba bọ silẹ lab; aṣọ rẹ gbogbo enia si ba si ẹrin

# Itan Ajapa Ati Elegbe Re

Ọjọ pẹ, Ajapa ti pa ẹiyẹ agbigbo, o ṣe eto rẹ silẹ fun awọn iyawo rẹ pe ki wọn dín ko din o wa gbagbe lati sọ fun awọn iyawo rẹ pe ki nwọn yọ awọn ori ẹiyẹ agbigbo yi kuro ti wọn ba se tan. oju ile igbin ti o nlọ nkan pupọ jagun bẹsi inu paripata tio ku bi rẹrẹ, pẹlu fila ati ṣokoto pẹlu bata to wọ, o ga. Nigbati yio fi de ile igbin, awon Ẹlẹgbẹ rẹ toku ti pewọ pesẹ sibẹ o nlu papa ti tọju gọngọ rẹ dada, ilu rẹ si tile dandan awọ oju ilu niyi ofunfun bi takanda,

Awọn iyawo igbin da ina tan onikaluku bọ ẹwu rẹ silẹ onikaluku wọn lo wọ aṣọ owo iyebiye kosi eyi to yẹ ki epo da si ninu awọn aṣọ yi wọn jẹun tan, o ko ọti silẹ bi wọn ti nicu ọti lọwọ, bẹni abi oju ilu bi takanda fi Gọngọ si i, eni ti o se ase lọ kọkọ ki ku inawo, lehinna, ni o wa da alajẹ wa lara ẹ ọ wọ ọ ni ti igbin, eni yio rọwa eni yio rọwa eni yio rọwa aṣẹ aṣe aṣẹ.

Gbigbọ ti igbin gbo ile ti o wọ ẹwu nla kan ati ṣokoto pẹlu fila lo gbe jade o si fun onilu pẹlu inu didun awọn Ẹlẹgbẹ rẹ wa bẹrẹ si si na owo gẹgẹ b o ti tọ ati bi o ti yẹ.

Won mura lati ma lo si ile Ajapa biwon ti bosi ita, onilu won tun fi 'owo si oju ilu rẹ to dabi takanda yi, orin tofi ilu na da nipe ṣai to foju di oba awo wo awo. eni foju doba awo wo awo, gbigbo ti won gbo orin yi ijo won wa yato, won bere si jo bi kokoro won agbada riyẹriyẹ, parinata Ajapa sin daya, daya bio ti ku sata die ki won de ile Ajapa o wa ranti pe on ko so fun awon iyawo on pe ki won yo ori ẹiyẹ agbigbo yi kuro ninu obe tio wa ninu isasun.

Kia ma fa gan, o ni ki awon onilu duro ati awon Ẹlegbe rẹ na pe on fe da orin aladun kan gbogbo won si fi eti sile lati gbo. Ajapa bere orin:- Iyanrinbo obinrin awun Tẹkokọ o obinrin awun, aki bani gbe kia ma mo ohun e ri, eyọ ori agbigbo kuro lobẹ o.

Inu awọn Elegbe're dede ti dun koja won bere si jo ijo gegebi akura ijo na ga bi nwon ti won ti tun de ehinkule Ajapa o tun ni ki wọn duro gegebi ti ẹkan o tun fi orin yi si won leti, ibẹni awon iyawo ti wa gbọ kia-mọsa wọn ti yọ tan ijo awon ọgbẹni yi wa ga lẹhinkule Ajapa riri ti Ajapa ri Yanrinbo bayi ọkan rẹ balẹ o ti mo pe won ti yo tan niyen. nigbana lo ni ki onilu rin nṣo wole won tun jo ijo yi ninu ile bakanna ki onikaluku won to ma joko si aye rẹ.

(Koiti pari)

## Iwe Ogun Oloye Oluwa De Kotu.

EKO. Awon ebi Oloye Amodu Tijani Oluwa ti ilu Eko se iwe si kotu Ganran wipe iwe ogun ti Oloye won. Oloye Oluwa fi sile jo aiyederu loju awon.

Awon ebi Oloye na ti o kowe lo siwaju Adajo kotu lati ba won wadi niwonyi, Lawani Oluwa Sikiru Oluwa ,Sanni Oluwa

Adajo kesi Ọgbeni Matthew Ayodele ti ise akowe oluwadi ki o lo yo eda iwe Ogun Oloye Oluwa na wa ki a fi we arawon wo, ki a le ri bi o ba je pe lododo ni nwon yi iwe na. Nigbati adajo wo o dahun pe, Ogun ti Oloye Oluwa fi sile ki o to ku je, Ọke kan abo Poun £30,000.) Nitorina ki awon ebi Oloye Oluwa lo san Poun mokanlelogun ati sile meji (£21 : 2. fun wahala ti nwon fi kotu se. Ko si eniti o yi ohun kan pada ninu re.





Kere o !

Ati ni orisirisi o g u n German to sẹsẹ de, fun emururu aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos

## Ogbeni Ikoku Tako Azikiwe

OGBENI S.G. Ikoku ti ... Alatako ... Ila Orun, tako ... Azikiwe wonle ninu ... Asofin wipe o ... rere je' ...



... ohun ti ... fiobn se ni wipe, bi ... ti n to ni nwon

o fi yan aṣoju sinu igbimo nla (Senate). Agbegbe ti awọn enia inu rẹ ba po ju adota ọkẹ lo, ki nwon yan aṣoju kan lo si igbimo nla ati awon agbegbe ti ko po to bẹ.

Ohun ti DR. Azikiwe wi tipe, ninu awọn agbegbe mejejila ti o wa ni agbegbe Ila-Orun, ki nwọn yan awọn aṣoju kọkan lati lọ si igbimọ ti gbogbo-gbo Ogbẹni Ikoku dahun wipe, eyiti DR Azikiwe wi yẹn ko dara, o lodi si ofin ti nwọn ṣe ni ọdun 1957, ninu igbimọ fun Ominira ilẹ Nigeria.

## ONISEGUN ILU NANDO KAN KU IKU ABURADI.

ENUGU. Agbo irohin p e okunrin adaunse kan ara ilu Nando, ti oruko re nje Onyekwere ni agbo wipe o wa li ore re kan ni Enugu ti oruko r e nje Timothy N...ku, si Oyi s i gbe lojiji tobe ti o gbo be yo si orun, ninu ile nwon fi wo si.

Awon olopa s i nwadi oro, na nipa i'u arun ti o pa okunrin onisegun na. Ejo si mbe ni ikawo awon olopa, nwon nwadi oro na siwaju.

## Itan Elegbeje Ado

Nigbana ni wọn tun wo fun ni akara kun, wọn ni tio ba ti ju si ẹnu, ti ilu rẹ ba ku bi ibusọ kan (one mile) ni yio to balẹ ti awọn ara ilu rẹ si wa pade rẹ Elegbeje - ado wa dupẹ lọwọ wọn fun iranlowọ ti wọn ti ṣe fun, titori tia ba ni kia to irin irin ibẹ si ilu rẹ yio to ọdun meta (three years) kio to de ilu rẹ na wọn tun wa ran ni ọwọ nipa irin na kia maṣa ... guo nw igbalẹ rẹ dani emi ko le mọ pe Ẹbọra lo sọ di igbalẹ rara ṣe aju arawa lọ ti ijakadi kọ kia ma fa guo ... fi akara yi senu lẹsẹkẹsẹ ni o si ti rin irin ọdun mẹta ni iṣẹju kan Nigbati o na duro o dupẹ lọwọ Olorun lẹmẹwa, emi ko mọ pe mo le bọ wa si ihin titi emi yio fi pari aiye mi mo tun dupẹ o Olọrun, bio ti dupe tan o wa wa onje la i jẹ o wa yọ ado o si fi nalẹ gẹgẹbi o nti ma nse teleri, onje orisirisi si ti de le kia masa o wa je o wa yo dada, o tun wa so pe Oluwa mo dupẹ lọwọ rẹ fun iṣegun tio fun mi yi.

Bio ti nse eyi tan, ni arabinrin kan wa nkọja lọ loju ọna, o wa ri, ẹru si ba arabinrin yi ni igbati ori ado pẹlu igbale (owọ) nile. Bi obinrin yi ti nlọ ni ọdẹ Elegbejeado ba pe, pe ko wa, ẹru si nba arabinrin yi ko fẹ wa sọdọ rẹ, o ni iwọ ko wa mọ mi mọ ni? obinrin pe on ko mọ won mọ, o ni emi Ọde Elegbejeado ti o ṣegun awon ole tọlọṣa) fun yin, ni ọdun kẹdogbọn sẹhin ni igba yẹn sini mo ti kuro ni ilu ti mosi lọ gbe ogun ti ọrọ Ẹbọra Ọṣundun ninu Igbo Ọṣundundun, mo si ṣẹgun rẹ.

Gbigbọ ti arabinrin yi gbọ eleyi, ofi ọwọ kan ilẹ o si ti fi kan aya pẹlu. o ni Oluwa mi modupẹ lọwọ rẹ fun abọ Elegbejeado ti mo ri yi gbogbo wa nilu lati so pe o ti ku opo enia si lo ti gbagbe rọ ni ile.

Nigbati o so awon oro yi tan Elegbe-ado wa da lohun pe ẹni ti Oluwa ko pa ebora kan kole pa, papa julo ati ẹda enia pẹlu. Ohun ti mo fẹ kio ṣe fun mi nisisiyi kio ba mi sofun awon ara ilu pataki julo fun oba ilu, pe emi yio wo ilu ni agogo mokanla ọla owuro kutukutu.

Arabinrin yi si fo eti pe ni agbara Ọlorun emi yio jiṣẹ rẹ gẹgẹbi a ti ran ẹru ni iṣẹ ti o si nfi tomo jẹ. Ni obinrin yi bayi ẹsẹ pada o si kori si ile rẹ.

(koiti pari)

## SANNI ADELE NPALẸ OGUN MỌ

O ta siwa leti ferọn wipe ọmọba Arẹmọ Sanni Adele ẹniti o nṣe aburo fun ọba Adele ọmọ bibi inu Buraimọh Adele npalẹmọ lati lọ ṣe Hadji ọdunni. A gbọ wipe ọmọ oba yi yio mu Alhaja kan dani.

Kabiyesi o, Alọbọ ni yio ẹ o.

## Ẹ LA WON YE WA.

Inu mi yio dun gidigidi bi a ba le ri ẹnikan ninu awon akowe rẹ, ti o ba le so idi abajo-oro wonyi fun akojo ogbon nile Yoruba

Kini idi re ti nwon fi npe Aka ni Odudu gberedu, ti nwon fi npe Lawani ni Amu-bi-oya ti nwon fi npe Buraimoh ni Dende, Ti nwon fi npe Salami ni Agbaje.

Emi ni, James Johnson.


# LAGOS RACE CLUB

## June Meeting, 1959.

**Saturdays 30th May, 6th, 13, 20th and 27th June, 1959.**

Provisional Programme and Entry Form can be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course.

NOTE:- No Entry Fees will be refunded after the draw has been made. Entries close at noon on Saturday 2nd May, 1959

23rd April, 1959.






## OGUN ARAN EJO INU

Aradan Worm Expello je ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buruku ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran beni o npa ẹyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan je 2/6 Owo ọkọ si je 1/.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES
18, Denton Bridge Street.
P. O. x 2. Ebute Meta







Printed Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467 phone 23370